The Chief Secretary to the Government


# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. No. 275 SATURDAY MAY 19, 1928. 4d

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



SECRETARIAT 23 MAY 1928



## *White's Radical Gonkiller.*

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si njẹ ki ọ ri aye wu arun mi silẹ.

# To Stop Your Aches & Pains

## Simply Use




For more than 40 years Sloan's Liniment has been used throughout the World. It is kept handy in many thousands of homes to give quick, warming relief from the pains and aches of Rheumatism, Lumbago, Neuralgia, Sprains, Bruises and other severe pains. No need to rub Sloan's—it penetrates and kills the pain instantly.

*Sold by all Dealers.*

Wholesale:
Fassett & Johnson, Ltd.
86, Clerkenwell Road,
London, England.

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RE

| Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|
| Odun kan 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*

## GBOHUN-GBOHUN.

MUNISIPA MA NGBERO IBI KAN, ORIṢA MA JẸ A T'ẸNU MI GBỌ!

Yiyin ni a yin si wa leti pe awọn Munisipa npete ati ṣi gbogbo moto akero to wa ni Ita Tinubu lọ si Balbina Street lapa ile Ọgbẹni Herbert Macaulay: nigbati a si bere Pantiwa, a sọ pe awọn Ọga Kotu ni nwọn sọ pe ariwo ti awọn moto wọnyi npa npọju tobẹ ti o fi ndi Kotu lọwọ nigbati iṣẹ ẹjọ riro ba nlọ nibẹ.

Njẹ Balbina Street le gba ogidinleje awọn moto wọnyi tan lai jẹ pe nwọn ni awọn ara adugbo ibẹ lara? Berebere ki ṣa ṣi bere.

ENMỌ PẸLẸMBẸ KITOYI?

Otitọ ha ni iro ti a gbọ ni *Monday* ọsẹ yi pe ẹnikan ti a gbọ pe ebi pa wọ'ra ti ko si ni õkan lọwọ lati ra onjẹ jẹ gbe ọmọ rẹ lọ si ọdọ Oyinbo kan pe ki o gba ọmọ na bi igbati Oyinbo ngba ekurọ fun tita, nigbati ebi pa ti o fẹrẹ yọ loju?

LỌWỌ IKU OJIJI OLUWA RERE GBA WA.

O jẹ nkan to ru wa loju pupọ nigbati a gbọ iku Ọgbẹni Belo Shẹlẹ ti Bamgboṣe Street loru mọju ọjọ ọsẹ to kọja yi, ẹniti joko ni ori pepele ile rẹ ni oru *Saturday* to ngbatẹgun titi di nkan bi agogo mọkanla ko to wọle lọ sun, ki agogo kan to lu, o di oku lai ṣaisan tẹlẹ, eyi ha ti jẹ o! "A mọ wipe lai si ina ati iro, ọmọ owu alagbẹdẹ kọ le ṣe iṣẹkiṣẹ kan, bẹ na ni lai si wahala ati iku, awa ko le ri iye," lọwọ iku ojiji Oluwa rere gba wa.

IYAN GARI D'ODE, ARA ILU.

Owo gari tun fo soke di sisi ati kọbọ meji (8d.) fun panu ti a ti nwọn ni tọrọ ri: ohun ti o mu eyi wa, gẹgẹbi a ti gbọ si, ni ipanpa ti awọn kan ninu awọn enia ilu ti a npe ni "ara oke" so lati ọja Ejinrin lati ma ta ni iye ti a wi yi fun awọn ara ilu, oro "Mayẹhun" ti awọn ara oke ti nwọn ta gari kakiri ita yi yio ma ṣe ilu leṣe, ti awọn agbagba ko ba tete mura ki nwọn si mọ ọna ti nwọn yio gba ki ebi maṣe pa pupọ enia ku, papa awọn ọmọde ti ko si ara wo ni nwọn ko le fi ẹtu funfun yi da tan: bi o ṣe wiwamu ni, gẹgẹ lo ṣe, bi o ṣe fifi epo pupa ro jẹ ni, gẹgẹ lo ṣe, bi o ṣe fifi ẹsẹ lu ni agaga, bi o ṣe riro jẹ ni, o wọ to gbajẹ, bi o ṣe titẹ ni ẹ a ni, ko si bo ti ri ni, bi o si ṣe jijẹ ni gbẹrẹfu ni ki a fi omi ti sohun, ko laifi. A fi ọrọ wiwọn gari yi kọ awọn agbalagba ilu lọrun, ẹ jọwọ ẹ ma jẹki ebi yọ elomiran loju sọ si ita nitori ọwọnlọwọn gari ode oni.

ENMỌ PẸLẸNBẸ.

Riyẹriyẹ li a ri awọn kan lapa ile alarun Ita Ẹlẹyẹ larin ọsẹ to kọja, nigbati a ṣe abere-ẹhin: a gbọ wipe ọkọnrin Kunakuna kan lo ko ohun jamba bowọ lọ fọ ile kan loganjọ oru mọju ọjọ na; nwọn ni awọn Onipo pẹlu Ọlọpa kan ṣe kongẹ igara na, nwọn le lọ titi lọ de apa ọna Kotomoru, ki ọwọ to tẹ ẹ, eyi ma ṣe kelebọ loju wa kẹ, njẹ bi enia ba lọ dubu ọfọn na nko, kilo ti le ṣe?

DẸ DẸ MERAWO.

Iwa ika ni awọn Dẹrẹba mọto miran ma nwa mọto tobẹ ti ogun a gboju wọn patapata lai bikita fun awọn ohun ẹlẹmi ti o nrin nilẹ; nigbagbogbo ni a ma nkọsẹ ri awọn owiwa wọnyi lati ma fi kẹkẹ wọn tẹ awọn ohun ẹlẹmi bi ẹran, adiẹ, pẹpẹiyẹ, aja tabi awọn ohun wọnni bẹrẹ rẹ, ti nwọn a si huwa andokiya lati ṣe ajo wọn; irufẹ iwa baun buru jọjọ loju wa, nitori awọn ẹsẹ pẹ-pẹ-pẹ lo ma ndi nla, abọ ọrọ o ẹnikeji.

MUNISIBA NDA BETE.

Rirekọja ti a nrekọja lo ni arin ọsẹ yi li a tun ri awọn Buka kekeke ti awọn Municipal tun ṣẹṣẹ nṣe si gbangba Anikantamọ, a si sọ fun wa wipe awọn

ẹniti o nta nkan wosiwosi leti ebute Idumagbo li nwọn nfẹ le wa sibẹ, a ri wipe Munisiba nṣe Buka fun lilo anfani ilu, nwon ha jẹ fi bun ilu lọfẹ bi ?

### IGBO-BIRI OKUNKUN-BIRI LO DIFA OJO KAN FUN ARINRIN-AJO-ORU.

Anu ṣe wa diẹ lati ri pe ode Lewis ni *sandgrouse* ṣokunkun pupọ ni aseko ti a ko ni anfani oṣupa, o ṣokunkun tobẹ ti o jẹ wipe bi ko ba si awọn imọlẹ ina kekeke ti awọn ara adugbo na ntan si ojude wọn, dajudaju enia yio fẹrẹ le fi igẹ sọ 'gẹ; nitorina a bẹ Ijọba ki nwọn gbiyanju lati fun Lewis Street ni anfani ina onimanamana (*Electric Light*) fun jamba ti o mbẹ ninu okunkun.

### O TO ABẸRẸ!

Gbukẹ ni a gburo lọjọ Atini ọsẹ yi pe nwọn ri Ọni nla kan ninu omi ti o wa labe Kereni Oyingbo (*Denton Bridge*), o ya gbogbo enia lẹnu lati gbo wipe bi ogunlọgọ enia ti pe biba si ori Kereni, ti nwọn nwo ọni na pẹlu ariwo ọni re! Ọni re!! nwọn ni ko tilẹ ta putu, afi mumu ti o nmu diẹ ti o si tun nyọ'ri lẹsẹkanna—Ọni ni gbẹgbẹlẹ yi, eyi ara!

### MUNISIBA DI IRUNMỌLẸ.

A tun ngbọ nisisiyi pe awọn ẹinti Munisiba yan lati ma fin ile ati awọn ekute nitori ajakalẹ-arun ti tun bẹrẹ iṣẹ yi, nwọn si ti de eti apa Lafiaji, lẹhin eyiti nwọn ti bẹrẹ lati idunta ti nwọn koi si ti fi ori rẹ ti sibi kan di bi a ti nwi yi—ṣugbọn a ngbọ lẹnu gbogbo janma pe bi awọn Munisiba ba ti fin ile kan tan, ti nwọn si ro wipe awọn ti pa gbogbo ekute ile na, nigbana ni ekute ṣẹṣẹ ma ni ki nwọn fo ki nwon niṣo ninu ile na, ki ti gbe? !!

### GBAJUMỌ ỌSAN BARAWO ORU.

Girigiri ti a ri awọn eio ti nwọn ntu yẹ-yẹ-yẹ ni Opopo Victoria ni owurọ ọjọ Alaruba ọsẹ yi mu wa tẹsẹ duro lati bere ẹrẹdi; a sọ fun wa pe ọkọnrin wonpari kan ti o njẹ Abudu Wabi lo lọ wo ṣabu awon Oyinbo Alagbon (P.Z) to mbẹ l'Ẹhin-ọgba lati pa wọn lara, aṣe ṣamọṣamọ nwọn ti dẹ ṣẹkẹṣẹkẹ silẹ, eyini ni pakute nla, ni ọkọnrin na ba fi lugbadi rẹ, bi ẹiyẹ o sọka, o wa di itakun to di erin lọna t'on t'erin ni yio lo—ki a ma fa gun lọ, a gbo wipe ṣẹkẹṣẹkẹ na di ọkọnrin yi biribiri, eyi ara!!

---

## IGBEYAWO.

Ni *Thursday*, ijọ kẹwa oṣu yi ni a gbe Omidan Stella Ibironkẹ George, ọmọ Ọgbẹni Josiah S. George ti Ile Iṣegun Ọba ni Oṣogbo, aburo Alufa J. E. George li Iṣabọ Abẹokuta fun Ọgbẹni Samuel Ọmọbọla Akinọla Akọwe ni P.W.D. l'Eko.

Agogo mẹwa-abọ ni akoko ti a da fun igbeyawo, ṣugbọn ki agogo mẹwa to lu, girigiri ni ẹsẹ nṣe ni Ṣọṣi Bethel, ibi ti a ni lati ṣe isin igbeyawo na.

Ko pẹ lẹhin agogo mẹwa ni ẹniti yio ṣe ọkọ iyawo pẹlu awọn ẹgbẹ rẹ de ninu Mọto pupa olowo nla.

O to nkan bi agogo mọkanla kọja ni Ọgbẹni Akin Adeṣigbin mu iyawo de, bi wọn ti de oju ọna gẹrẹ ni Alufa Abọyade Cole pe orin kini eyi ti a ti ṣe akanṣe rẹ tẹlẹ,

Ma tọju wa Baba Ọrun
Larin 'damu aiye yi
Pa wa mọ ko si ma bọ wa
A ko ni n'ranwo miran
Ṣugbọn gbogbo bukun l'a ni
B'Ọlọrun jẹ Baba wa.

Bi a ti nkọ orin yi bẹ ni iyawo ngbe ẹsẹ lọkankan titi o fi de ipo rẹ; bi o si ti de ipo rẹ ti ẹgbọn rẹ ti o mu u wa fi i silẹ bẹni Ọgbẹni Akinọla sun mọ iyawo timọtimọ ti Alufa Abọyade-Cole si nba iṣẹ isin rẹ bọ.

Ọpọlọpọ enia lo wa si ibi iyawo yi ṣugbọn awọn diẹ ti a ranti niwọnyi:—

Mesdames C. A. John, A. J. George, Adina Pedro, A Faderin, Mari King, J. S. Williams, Sally Adeṣigbin, Christiain George, Maryfan George, Abọsẹde Adeṣigbin, Emily Macaulay, Nancy Potts-Johnson, Ige Cole, Comfort Bailey, Ọderinde, Ọlabisi Blaisze, Lucy Franklin, Ibiluade Derby, Faustino, Grace Alder, Ṣubulade Smith, Adetoro Hithersmith, Janet Cole, Flora Elliott, Beatrice George Akinkunmi, Rabiatu, Taiwo Bailey, Flora Macaulay, Sharp, Jaiyeola Olawunmi, Safu Ajai, Rachel Akiọde Oyebola Ajai, Adeline Bakare, Patience Adeniyi, Oyinlọla Akiọde, Ibironke Ajọṣẹ Elen Ayọrinde, Confort King, C. O. Porter, Ebun Adeṣigbin.

Messrs. Oke Adeṣigbin, J. Mosalewa Thomas, Henry Willoughby, Ogunlana, Ebinisi, Hudson Cole, Jonathan George, Oshin, Olamide Ajai, Ayo Savage Sanya Akiode, T. B. Layeni.

### ỌMỌ IYAWO.

Layinka Adeṣigbin, Onikẹpọ Adeṣigbin, Adebisi Adeṣigbin, Oluremi Adeṣigbin Suberu Adeṣigbin, Olufunmilayọ Adeṣigbin, Adebisi Akiode, Iyabọde Akiode, Adebisi Davies, Layewọla Alder, Agbekẹ Alder, Ayodele Wiliams, Olurẹmi Oderinde, Ọlabisi Ayorinde, Babatunde Adeṣigbin, Jaiyẹola Maja.

Ọgbẹni Jonathan George lo fi iyawo fun ọkọ Ọgbẹni Henry Willoughby lo wa lori Duru, Ọgbẹni E. A. Franklin lo ṣe akoso ti *Cake* gige, labẹ itọju ẹniti ohun gbogbo lọ tọwọ-tọwọ ati tẹyẹ-tẹyẹ.

Jijẹ, mimu nlọ lẹsọlẹsọ pẹlu ilu oriṣiriṣi ati ijo titi di agogo mẹfa abọ ti ọkọ iyawo pẹlu awọn

ẹgbẹ ati ọrẹ rẹ wa lati mu iyawo nwọn ; a si fi adura sin iyawo bọ si ode lọ si ile ọkọ rẹ:—Ori re ni ti awo.

IREWỌLE.

---

## ATUNBỌTAN-DUNIYAN.

(A RI ORI OLOGBO L'ATẸ).

Lati ọwọ Kekere Awo.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

Lẹhin iku Aṣipa Ọba Adó, ni Ido ibiti nwọn ti npe ri ni Ile-Ọlọfin, ẹniti o nṣe ọmọ Aṣipa jọba ni Ekò ninu ọdun 1630, ni iṣiro rẹ o jẹ ọdunrun ọdun o le mejidinlọgbọn nisisiyi.

Gẹgẹbi ọpọlọpọ itan ti pọ ni di awọn Ọba gbogbo ti o ti njẹ ni ilẹ yi ri titi o fi wa kan ọmọ-Ọba Eṣugbayi, eyiti a ko le gbiyanju loni lati gbe ẹnu le nitorina, a o mura nisisiyi lati fi orukọ awọn ọba wọnyi han nyin ati iye ọdun ti olukuluku wọn njọba ni ilẹ yi, ki a to bẹrẹ si sọrọ wa :

| | | | |
|---|---|---|---|
| Ọba | Adó | — | 1630—1669 |
| „ | Gabaro | — | 1669—1704 |
| „ | Akinṣemoyin | — | 1704—1749 |
| „ | Ologun-Kutere | — | 1749—1775 |
| „ | Adele | — | 1775—1780 |
| „ | Ọṣinlokun | — | 1780—1819 |
| „ | Idewu-Ojulari | — | 1819—1834 |
| „ | Oluwọle | — | 1834—1841 |
| „ | Akitoye | — | 1841—1853 |
| „ | Kosọkọ | — | 1845—1853 |
| „ | Dosunmu | — | 1853—1885 |
| Ọmọba | Oyekan | — | 1885—1900 |
| „ | Eṣugbayi-Eleko | — | 1901— |

Gbogbo awọn Ọba ti a darukọ wọnyi lo ni ijoye gẹgẹbi iṣẹdalẹ, gbogbo awọn ojoye wọnyi lo ni orukọ wọn ati pẹlu ẹwẹ olukuluku lo ni iṣẹ tirẹ bi nwọn si ti ni iṣẹ wọn nipa oye bẹni ipo wọn ju ara wọn lọ.

Ipo kini ni oye jijẹ wọn, ati orukọ awọn ojoye ti o jẹ aṣiwaju ninu oye ni wọnyi:

Onilẹgbalẹ, Eletu Odibo, Ologun, Eletu-Ijẹbu, Eletu Iwaṣẹ, Eletu-Awo, Ologun ti o mbẹ ninu ijoye to orisi mẹta tabi mẹrin.

Ipo keji ninu oye jijẹ ati orukọ wọn : Olumẹgbọn, Aromirẹ, Oluwa, Onişiwo, Ọjora, Ọlọtọ, Onikoyi, Oniru, Onitọlọ, ati Elegunsi.

Ipo kẹta wọn, awọn ẹniti nwọn npe ni Ọgalade tabi Adifa fun Ọba ni Ọbanikoro, Onisẹmọ, Ọpẹluwa, Onimọlẹ, ati Mọdile.

Ipo oye kẹrin eyiti a npe ni Abagbọn *War-chiefs* ni Aṣọgbọn, Suẹnu, Egbe, Aiyemẹsan, Bajulu, Ṣasi, Aṣasi, Kakawa, Salawẹ, Ipọsu, Ṣaṣọrẹ ati Okolo.

Awọn ojoye ti o mbẹ ni ipo kini ati ekeji ni a npe ni Idẹjọ awọn Idẹjọ wọnyi si ni onilẹ awọn lo si lagbara lori ilẹ yi julọ, lẹhinna ẹwẹ ninu wọn lo nfi Ọba jẹ, gẹgẹbi ẹto ti o ti mbẹ lailai.

Awọn ojoye Ọgalade marun ti a darukọ, ti o mbẹ ni ipo-oye kẹta (Ọbanikoro, Ọpẹluwa, Onisẹmọ, Onimọlẹ ati Mọdile) jẹ awọn oloye ti o ndifa *(Babalawo)* gẹgẹbi a ti wi ṣaju.

Awọn oloye ti o mbẹ ni ipo kẹrin ti a pe ni Abagbọn jẹ Balogun fun Ọba, ṣugbọn ninu ipo awọn ojoye kini ti a pe ni Idẹjọ awọn mẹrin lo wa ti nwọn nfi Ọba jẹ, awọn ni oloye Eletu-Odibo, Onilẹgbalẹ, Eletu-Ijẹbu ati Eletu-Iwaṣẹ, aiye ma si ti yipada ni Eko nisisiyi, bi o wu wọn, nwọn le yan sabarumọ pe ki o fi Ọba jẹ, bo fẹ bi ko ni Abẹrẹ (*Blanded Sword*) lọwọ ko laifi bi o ba ṣa ti fi ara kọ ọkan ninu awọn ojoye ti a darukọ gbẹhin yi, ọran ti pari, ki nwọn ma jọba lọ ku, ko si kuku.

Ni aṣọ ija Ọba Akitoye ati Ọba Kosọkọ, Ọba Akitoye fi ilu silẹ lọ si Abẹokuta Ọba Kosọkọ ko si Iga Idunganran nigbana o sọ wipe ki Oṣodi Tapa lọ gbe ori Ọba Akitoye wa fun o, lati Abẹokuta yi ni awọn Ẹgba fi ṣe atilẹhin fun Akitoye ti o fi tatare lọ si ilu Agbadayigi lati ibẹ lọ si Fernandopo nipa amọran oyinbo kan ti o njẹ Beecroft, lati ilu Fernandopo na ni Ijọba Igẹsi ti ba Ọba Akitoye wa si ilu yi lati ṣe atunṣe ija on pẹlu Kosọkọ—oyinbo Beecroft pẹlu awọn enia diẹ ba a wa si Eko lọjọ karun oṣu *November* ni ọdun 1851, a ko ni ọrọ pupọ lati sọ nipa eyi.

Ni aiye Oba Adele ni ija kan ṣẹlẹ larin on ati Ọba Ọṣinloku, ija yi mu ki awọn ara ilu sopanpa pe o ni lati fi ilu silẹ—gẹgẹbi o ti jẹ wipe awọn Ijọ so nigbana pe Ọṣinloku lo kọ awọn pe ki nwọn ba Ọba Adele jagun, Ọba Oşinloku bura fun ilu titi pe ọran ko ri bẹ—sibẹsibẹ awọn ilu ko ni igba gbọ si i, nwọn ni o ni lati yera kuro ni ilu tulasi kayan doro, ki a ma da lọ wọnna, Oṣinloku fi lọ si ebute Idumagbo o fi Abẹrẹ ọwọ rẹ na omi o si fi ẹsẹ wọ omi lọ si Ijẹdẹ eyiti o mu ki Ṣilokun ṣepe lọjọ na.

Ni aseko ija Ọba Akitoye ati Kosọkọ, oloye Eletu-Odibo fi ilu silẹ gẹgẹbi aṣẹ Ọba eyi ki iṣe nipa lile ojoye kuro ni ilu, nipa ifẹ Ọba ni, Ọba lo ran nişẹ ko da lọ fun ararẹ, bẹni nwọn ko si wa kuro ni ilu.

Ọba Dosunmu jọba ni ọjọ 22 oṣu June, ọdun 1853, ni ọdun kẹjọ ti o gun ori oye ni Iga Idunganran ni Ijọba Igẹsi fa Asia won si ilẹ yi nipa iwe Adehun *Treaty of the cession of Lagos*, ti nwọn ṣe lọjọ kẹfa oṣu August ọdun 1861,—ni aseko Ọba

rẹ ko si rigbodiyan larin ilu bi ti aiye Akitoye pẹlu Kosọkọ, bikoṣe igba ti ija nla kan ṣẹlẹ larin Ọba Dosunmu, Ajasa Apena, Balogun Aṣogbọn, Taiwo Olowo ati awọn ẹlomiran jakanjakan, ija na ni nwọn npe ni ija Ọba Dosunmu ati Taiwo Olowo, awọn agbagba yio ma ranti bi ija na ti le to bi a ti nwi lọwọ yi.

Nipa ija na ni Ijọba fi mu awọn enia marun Ajasa Apena, Arẹ Kakanfo, Agoro, Okọya, Obirikiti ti nwọn si wa wọn lọ si ọna ilu Aganyin *Gold Coast* lojọ kẹtadinlogun oṣu September ọdun 1884, ṣugbọn nwọn da wọn pada ninu ọdun 1885, ọjọ kẹrinlelogun oṣu September.

Ọba Dosunmu w' aja, Oyekan akọbi rẹ gun ori oye ninu ọdun 1885 larin oṣu March, a ko ri ija-igboro tabi ijakija kan ni sanmọni rẹ debi ti a fi le sọ wipe ẹnikan fi ilu silẹ—ṣugbọn larin Ọba rẹ ni awọn Ijọba-Igẹsi pẹlu awọn ara Ijẹbu-Ode, Gomina G. T. Carter, K.C.M.G., lo mbẹ nihin nigbana.

Lẹhin ti Ọba Oyekan waja, Ọba Eṣugbayi Eleko gun ori oye Iga Idunganran Ọba Dosunmu *House of Docemo* ninu ọdun 1901, ọdun kejidinlọgbọn loni, nipa ifohunsi Gomina William MacGregor, M.D., K.C.M.G., G.B.

Ni gbogbo aseko awọn Ọba ti a ka fun nyin yi, eyiti o ti bẹrẹ lori Ọba Adó ni ọdun 1630, dajudaju a koi ti fi igbakan gbọ ri, bẹni nwọn ko fi sọrọ sọ fun wa ri pe awọn Idẹjọ kan Ogalade tabi Abagbọn dide ni arin ilẹ yi mu ọna kan pọ pe nwọn njẹ faji lọ si ibikibi, laijẹ wipe o han fun gbogbo ilu ri, bi irufẹ ohun bẹ tilẹ han fun ilu mọ lasi tabi-tabi ati iyapa ẹnu, ambọsi-bọsi ohun ti a ko i ti ri ni ilu yi arara.

Ọna ti ojoye kan fi le di gbẹrẹ lọ si ẹhin-odi ni pe aiyaṣebi o ni sababi pataki kan eyiti o si gun Ọba lọwọ ati lẹsẹ ti o si ni lati jẹ aṣẹ ati imọran Ọba ti o ba mbẹ lori oye.

Ti rogbodiyan kan ba Ọba, awọn ojoye ni ẹtọ ati ẹyẹ lati gbaruku ti Ọba lai yẹ lai gbo, nitori ki Ọba na ma ṣe binu si ojoye ti o ba tadi mọ ẹhin.

Ni aseko kan, Ọba ti o ba jẹ ni ilẹ yi, on ni gbogbo ilu mọ ni Olori gbogbo ilẹ enia dudu patapata, nitori igbereko ni awọn ilu iyoku ti nwọn ni Ọba jẹ fun ilẹ yi, Ọba kọba kan kole ti ilu oke tabi gbogbo ilẹ enia kan wa lati jẹ gaba lori Ọba ti o mbẹ ni ilẹ yi, nitori pe ilu yi le jẹ fila fun awọn ilẹ *Nigeria* patapata.

Ọba kọba tabi ojoye k'ojoye le ti ibikibi wa si ihin, nwọn si ni lati ni saba bi pataki kan, Ọba igbereko tabi ti ilu ati awọn ojoye ibẹ le ba ohun pataki wa si ilẹ yi ti o ba wu wón, ko ni laifi kan rara—gẹgẹ bi Ọba kan tabi ojoye kan ti ṣe le ti igbereko ilẹ yi wa bẹni awọn Ọba ilẹ yi tabi awọn ojoye le lọ si ilu oyinbo ibiti a mọ ni Alakoso fun gbogbo ilẹ enia dudu, bi nwọn ba si ni lati lọ si ilu oyinbo, a jẹ wipe nwọn ba ohun pataki lọ.

O ya wa lẹnu lati ri wipe awọn ojoye melo kan eyi ti a mọ oloye Ọbanikoro ( Adamọ Akẹju) ni Olori nwọn mu ọna ilu oke ( Ibadan ati Ọyọ ) pọn lọjo karun oṣu yi kanna nwọn gba ọjọ marun ni ẹhin-odi nigbati nwọn de ọhun nwọn ri Balẹ ti o wa ni Ibadan, nwọn si kuro ni Ibadan, nwọn lọ si ọdọ Alafin ni Ọyọ ; gẹgẹbi o ti jẹ wipe nigba ti nwọn yio lọ ogunlọgọ enia ni ilu ni ko mọ ohun ti nwọn nlọ fun, awọn apakan nsọ wipe nwọn nlọ wo Idajọ ti nwọn nda ni ilu oke, awọn ẹlomiran si nsọ ọrọ mọṣaṣi si wọn lara ohun ti o mu ọrọ kantankantan wọnyi wa ni pe, irufẹ idalẹ bẹ jẹ ohun akọtun fun wọn, eyiti sababi iru irin-ajo bẹ fara sin fun ọpọlọpọ enia ni ilu bikoṣe awọn isaigbe alatilẹhin Ọbanikoro nikan.

Nigbati nwọn si de lati Ọyọ, awa koi ti mọ ohun pataki ti nwọn ṣe lọhun—gẹgẹ bi o ti jẹ wipe ko ye wa bi Ijọba lo gba wọn ni imọran iru idalẹ bẹ tabi yala awọn tikalara wọn lo ba ara wọn gbimọran rẹ, ṣugọn a gbọ ṣuwaju ki nwọn to lọ si Ọyọ pe Captain Ross, ( Senior Resident of Ọyọ ) lo fi irufẹ idalẹ bẹ si iwaju wọn, ṣugbọn nigbati a ko ri gbọ ninu iwe-Ọba tabi *Gazette* ko jẹ ki awa le gbagbọ, nipa bayi ni idalẹ bẹ fi jẹ ribiribi ati ohun ti o ṣokunkun loju ọpọlọpọ enia, o yẹ ki ilu mọ irufẹ ohun ti idalẹ bẹ jẹ ; tabi ko yẹ ?

Nigbati nwọn fi Ibikunle Akitoye jẹ Oye Olori-ile-Ado, awọn ọmọ ẹhin rẹ nkọrin bayi pe :—

Ẹniti ko gbọ t'Ọba
Yio re'le Ọyọ
Awọn ngbọ t'Ọba.

Itumọ orin yi jasi pe ẹniti ko gbọ ti *Prince* Ibikunle yio lọ gbọ ti Eṣugbayi ni Ọyọ.

Nigbati nwọn nkọrin bẹ nigbana, nwọn ha lero pe awọn tikalarawọn le ba Oloye Ọbanikoro lọ si Ọyọ ni ọjọ karun oṣu ti a wa yi ? Bi nwọn tilẹ ni iru ero bẹ, a jẹ wipe nwọn ko gbọ ti Ọba mọ nisisiyi lo ṣe jẹki nwọn gba ọna Ọyọ lọ, ambọtori idalẹ na ko ye gbogbo enia ni ilu—sibẹsibẹ o tọ o yẹ ki ilu mọ sababi pataki ti nwọn lọ si Ibadan ati Ọyọ fun, ti o si fi jẹ wipe nwọn pada wa si ile larin ọjọ kẹrin ti nwọn lọ ; ẹ ba fi ye ilu i ba dun pupọ nitori orin ebu ( *abusive language*) nikan li a gbọ pe nwọn mu bọ Ọyọ.

Emi ni ti nyin nitotọ,

KEKERE-AWO.

---

## IFE NEWS.

### IFE AFRICAN TENNIS' CLUB.

Healthy Recreations generally tend to strengthen the physique of a man and teaches him not only to cultivate the essential qualities of

a Sports man but also to understand how to play the game. To achieve success without being swollen headed, and to suffer defeat without grumbling. Africans as a Race have their own national recreations like Wrestling (gidigbo) "Wari" playing (ayo) etc., etc., but these are now being superceded by foreigen Sports like Cricket, Tennis, Billiard, etc. A craze for Tennis playing is manifesting itself here and there, and like an infections disease, it has spread to Ile Ifẹ and found ready victims among some notable youngmen of that community.

There a tennis court was erected so to say, and 7th of April last was an epoch-making day at Ifẹ when the opening, in the presence of a large crowd of the new Club Tennis Court under the Chairmanships of Prince Adeyẹmi of Ifẹ became an accomplished fact The ceremony was open with a short address by the Chairman who expressed an unqualified pleasure not only to preside over the gathering, but also to visualize such a phenomenal progress and advancement in his father's country, during his father's reign. He hoped to see the town progessing as well in wisdom, charity, finance, morality while remaining loyal to the British Government and all the constituted authorities.

The presence of Europeans he said was very gratifiying and the more they come, the more the merrier.

Other speakers include the Chiefs who represented the Ọni at the function. Speeches being over, the Chairman announced that the Court be opened by the Captain of the Club Mr. I. H. Williams and Mr. Ogunjobi the paymaster—single play. After some playings which were very interesting and exciting, refreshments followed and the group photograph of the Club was subsequently taken.

The function was brought to a close by singing the National Anthem at 7 30 p.m, and the blessing of God manifested itself by the shower of rain which drizzled afterwards

Thus ended a brilliant and most successful Function. God save the King.

## WILL THERE BE ANOTHER WAR?

A report has reached us of meetings that have recently held in Manchester by two Gentlemen, "who have travelled seven thousand miles for the sole purpose of delivering a message," The visitors are the Rev. C. E. Bitzold and Dr. Galbraith of Vancouver, "both men of culture as well as Zeal." They are paying their own expenses and ask for nothing but a hearing. During the war they were in the fighting—line. and it was while in the trenches that they has a new revelation in regard to Bible prophecies. They believe that there will soon be another great war, which will continue until 1930. A situation of "Stalemate" will ensue, lasting three years. Then the contest will be re-newed; terrible weapons of destruction will be used, cities will be blotted out, and countries devastated. Yet they believe that this may be averted if the nations will turn in penitence to God, and they urge the need of national repentance and prayer. To further this purpose a League has, we understand, been form, with Mr. John Ashworth, a well-known Quaker, as President; Mr. Pugh of the Bibie Society, as Treasurer; and Mr. J. A. Gray,, of Whalley Bridge as Secretary.

*(The Christian Herald, April, 26/4/28.)*


## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Ọṣupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku olegbo.

EKO AKETE

EKO, SATURDAY, MAY 19, 1928.

## ELEKO O! ELEKO! ELEKO ỌMỌ-ỌBA !!!

Ko si bo ti ri ni irohin ti a sọ fun ni lọsẹ yi nipa ti ogidinleje ero ti nwọn nwọ lọdọ Prince Eṣugbayi Eleko ni Ode Ọyọ ni akoko igbati Ọbanikoro ati awọn isangbe rẹ lọ ki Alafin: ki iṣe pe Prince Eṣugbayi lọwọ ninu ilọ ti Oloye Ọbanikoro pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ lọ si Ọyọ o, agbẹdọ: ṣugbọn ninu ọgọrọ awọn enia wa ti ọrọ Prince Eṣugbayi Eleko dun lo lọ si Ọyọ ni igba ti a nwi yi, ti nwọn si parapọ sọdọ Ẹni Ilu nfẹ na, ti nwọn si ngbe ibẹ nriran awọn ti nwọn nsujada fun Alafin pẹlu ika tita mẹsan mẹwa lọna "k'ẹpẹ! k'ẹpẹ!!" Ẹ jẹki a bi ara wa lere ni gbolohun ọrọ kan tabi meji: o ha jẹ pe Prince Eṣugbayi Eleko gbe nkan fun aimọye enia nibi, ni Abẹokuta, ni Ibadan, ni Kano, ni ilu Aganyin, ni Saro, ani ni ilu Oyinbo jẹ lo fi jẹki ifẹ wọn si ki o tubọ ma pọ siwaju ni, kaka ki o dinku? Agbẹdọ: afi ọmọ ana tabi ọmọ agbo lo ku ti ko mọ sababi ti o ṣi ọkọnrin kọkọ̃bọtọ, baba Layide nipo pada lọ si ilu okere lati ọjọmọjọ yi wa, ko si si igbati iwe irohin kan le sọrọ rẹ ki gbogbo ilu maṣe takiji.

Lati igbati a ti gbọ pe ẹjọ rẹ ti di riro ni ilu Ọba ati pe idajọ nikan lo ku ki a gbọ ni o ti jẹ ifẹ ẹgbagbeje enia pe ki Ifa Idajọ na maṣai fọ rere, eyini ni pe ki olukuluku enia ti o ti nwa ni hilahilo nipa ọrọ na maṣai ni ayọ ati inu didun si igbẹhin ẹjọ na.

Ni ẹnu ọsẹ diẹ sẹhin ti o kọja yi kọ ni idagiri da gbogbo Eko pe ọwọ ilu ti tẹ eku ida nipa ẹjọ na: a ko le sọ iye ọpọ enia ti nwọn bi wa bi lotọ ni Oriṣa ti pa tira (ẹkun: bi Adedoyin ati James nrin ni Titi *Street*), ko si ọrọ meji ti nwọn ma sọ (ikoṣe ọrọ idagiri yi bi o ṣeṣi ri Agbekẹ pẹlu Abẹbi ti nwọn njumọ kiri akara olororo pọ, ko si ọrọ on un meji ti nwọn ma mu sọ bikoṣe ọrọ kanna yi. Irufẹ ãjo bayi ki iṣe ohun meji bikoṣe ifẹ titobi ti o wa lọkan olukuluku awọn ara wa wọnyi si Ẹni Aiye nfẹ na

O ha jẹ pe gbogbo enia ti nwọn gba ọrọ Eleko dun ni Ọmọ Alade na mọ tan? Nda. O ha jẹ pe o fi owo ribiribi bẹ wọn ni ki nwọn to ma jẹ ọrọ rẹ lẹnu nigbagbogbo bi ẹni njẹun? O ti o! a ti lã pe o ni ẹniti ọkan enia nfa si papa nipa ti ọrọ Eleko ti ibẹrẹ ati iṣe ara si wiwa lọ rẹ nipa aṣẹ Ijọba ko ṣẹhin pupọ ninu awọn enia wọnyi.

Ṣiwaju ọdun 1925 tani ko mọ pe Prince Eṣugbayi Eleko ni Ọba Iga? Tani ko mọ pe Olori Ile Dosunmu ni? Ko si, ṣugbọn idarudapọ ti o ṣẹlẹ lẹhin akoko yi kọ lo sọ "IOfe di ara Ọyọ" ti "Aganran di ara Ẹdẹ", bi o si ti jẹ ifẹ gbogbo ilu ni pe ki Ifa maṣai fọ rere, Igede ti a le fọ ni pe

"Eleko! Eleko!!
Ile ni Abọye nbọ̃ si, Alọye."

---

## MALU TI KO NI IRU, ỌLỌRUN L'O MBA LE EṢINṢIN.

[ WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI AJANAKU. ]

Mo bẹrẹ f'oji,

Oniruru iya li o mbẹ li ode aiye: iya wọnyi si pọ tobẹ gẹ, ti a npa a li owe wipe, "bi a ko ba to lati kọ iya, iṣe ni a njẹ kun u."

Olowo nfi iya jẹ talaka, ọlọgbọn nyan-ga omugọ, alagbara nda họ-o ko-si-alabaro, idin nṣọ ẹran di ibajẹ, eṣinṣin njẹ Kudayisi, ṣugbọn eṣinṣin ti o ba jẹ malu ti ko ni iru, o njẹ majele.

Gbogbo ilu Enia dudu, eyiti Ijọba Enia Funfun pin li arin ara wọn gẹgẹ bi ogun (Estate,) ati irandiran baba nla wọn dabi malu ti ko ni iru, nitorina Ijọba Oyinbo-k'Oyinbo ti o ba si fi ara rẹ si ipo alailanu eṣinṣin Kano, ọsan kan, oru kan, ni Ọlọrun ma gba Sọnde (Sunday) li ọwọ rẹ, ti O ma gbe Satide (Saturday) le e lọwọ: ọran epe kọ.

Nigbati a ba ranti emo nla ti Ijọba Belgian fi oju awọn ẹlẹgbẹ wa ni Kongo li akoko kan ri ban, nigbati a ba ranti iwa bi o ba a, ki o pa a, bi o ko ba a, ki o bu u li ẹsẹ, ti awọn enia Funfun ara

Amẹrika hu si awọn ibatan wa ri ni ilu wọn li ọhun, ti a ba ranti ọwọ lile ti Franse fi mu awọn Dahọmi ri; ani, ti a ba ranti igbe Oro ! Oro ! ! ti a gbọ wipe awọn iyekan wa ti o ti wa li abẹ Ijọba Jamani ri nke ni agbegbe Kamarun, a ko le ṣai dupẹ li ọwọ Baba fun anfani Ijọba Gẹsi ti O fun awa ara ihahin.

Ko ṣe wipe awọn Gẹsi na papa ko nfi ofin miran banijẹ lẹkọkan, ṣugbọn gẹgẹ bi ekute, nwọn ko jẹ gbagbe ati fẹ oji tabi atẹgun si ibiti nwọn ba bujẹ na li ara wa.

Ọmọluwabi Enia Dudu wo li o le wipe on mọ itumọ ki a ma fi bi ile ti tobi si san owo omi, yala eni meji tabi mẹta pere li o ngbe inu rẹ, itumọ ṣile mẹwa ọdọdun owo iwe aja, itumọ ẹran ewurẹ kiko kiri adugbo ti ko nṣe Opopo nla, itumọ adọta pọnwun li ọdun owo iwe ọti tita, lẹhin ti ẹniti o fi owo ranṣẹ oti na ni ilu Oyinbo ti san owo ibode fun Ijọba, itumọ pọnwun mẹrindi-lọgbọn ti Onigbanjo (Auctioner) nsan li ọdọdun fun Ijọba, nigbati ko nṣe wipe bi Onigbanjo ba ta ọja, ti ko fi owo jiṣẹ, Ijọba yio san owo fun Ọlọja.

Itumo ki ẹniti a jẹ li owo ma san owo onjẹ alagbeda rẹ ti o wa li Ẹwọn-igbese, nigbati ẹniti o ja ni li ole, ti ko ji owo Ijọba, ti Ijọba fi si Ẹwọn, ti o nṣe iṣẹ ọfẹ fun Ijọba l'ai j'ọsin rara fun olufisun rẹ itumọ ofin ki Enia Dudu mẹta pere wa ni Igbimọ ilu (Legislative Council) pẹlu Oyinbo bi ogoji, itumo ofin Arede, wipe ki aya ku, ki ọkọ fi gbogbo owo ati ohun-ini aya na mu ọti tan; tabi ki ọkọ ku, ki aya nikan ko gbogbo ile ati ọna ọkọ na, laibikita fun iya tabi ẹnikẹni ninu Ẹbi ọkọ; itumọ ofin wipe ki aya Alarede di panṣaga, panṣakuta, ki ọkọ ma le ba a ro ẹjọ ikọsilẹ, ayaṣebi o ni owo ati haya Lọya ti yio tako on papa fun aya na, itumọ ki Oyinbo oniṣe Ọba ma gba Duty Pay li oṣoṣu, ki enia Dudu ma ri Duty Pay ṣe ọmọ ẹnu pẹlẹ; itumo ki Dokita Oyinbo ma gba owo pupọ ju Dokita Enia Dudu bi Oguntọla Sapara, I.S.O., Kubọlajẹ Faderin ati Ladipọ Oluwọle lọ, nigbati o jẹ wipe ọga nta, oga nra bakanna ni gbogbo wọn jẹ ninu iṣẹ Dokita na; itumọ ofin Assessor tabi Juri mẹta ti Onidajọ le ṣai ka idalare tabi idalẹbi wọn fun arufin si, nigbati ofin arumọjẹ bayi ko si ni Ilu Oyinbo papa.

Iru ofin wọnyi ati omiran bẹ li o dabi ekute bunijẹ-fẹni fuu awa ara Eko nisisiyi, eyi ti o si buru ju gbogbo rẹ lọ ni iwa ti awọn a-d'agba madanu ti o npe ara wọn ni Aṣaju wa lailai nhu, ati I concur, I concur, eyiti nwọn fi ngba eruku ti awọn masandoki ofin yi l'ẹsẹ.

Ọba Ilu Oyinbo (God save the King) ko de ilẹ yi ri, Ọgbẹni Ramsay MaCdonald, Baṣọrun Ọba ko de Okun Ileke ri, bẹni Ọgbẹni J. H. Thomas, Secretary of State tabi Olutọju ilu ti o wa li abẹ Ijọba Gẹsi ko mọ ibiti a npe ni Langbasa. Nitori-na, ohunkohun ti Gomina ba sọ fun wọn nipa ilẹ wa ni nwọn ngba, titi a o fi ri Iwe-irohin wa ti yio ja wọn ni koro, ti nwọn ba ṣ'okobo. Ọpọlọpọ ohun ti Gomina si fi nranṣẹ yi le jẹ ọrọ ti nwọn ba gbọ li ẹnu awọn Langalanga ti o ndu oye C.M.G. lati jẹ.

Gomina miran, ẹwẹ, ni li ọwọ fun ara rẹ, o si di si ẹru pẹlu. A ha le gbagbe Gomina Sir Frederick Lugard, li akoko ẹniti ọpọlọpọ ofin aramukandu bi Provincial Court Ordinance, ati oniruru ofinkofin miran wọ ilu.

Ti a ba yọ ọwọ Eko kuro, gẹgẹ bi ofin Provincial Court Ordinance yi, ṣaṣa ilu miran ni Nigeria ni enia le haya Lọya fun ẹjọ, ibaṣe wipe ẹsun ẹjọ ipania ni a fi sun oluwarẹ na, Oyinbo ti ko tilẹ mọ adugbo ibiti Inns of Court ti awọn Lọya nkọ ofin wa ni Ilu Oyinbo le da enia li ẹbi iku, bẹni ko si ibiti Oyinbo ko le haya Lọya ro ẹjọ ni Nigeria, afi ibiti ko ba si Kotu Ijọba Gẹsi.

Sẹria pa ofin buruku yi rẹ, ijakadi kekere kọ ni a ti ba Ijọba ja nitori rẹ. Awọn ẹgbẹ National Congress of British West Africa si ṣe wahala pupọ lati ri wipe ofin aramukandu yi di ologbe. Ofin yi di eṣinṣin, o njẹ awọn malu wa ti ko ni iru kiri, ṣugbọn o dabi ẹni wipe Ọlọrun papa fẹ bẹrẹ si ba wa le eṣinṣin na.

Iporogan ọrọ kekere kọ ni Igbimọ Ilu Oyinbo (House of Commons) ba ara wọn ta ni ọjọ kọkanla oṣu April ọdun 1924 ni ireti ati fi ọkan ninu ogun (Estate) ofin buruku—Provincial Court Ordinance, eyiti Gomina Sir Frederick Lugard fi silẹ fun ilu wa ranṣẹ si okun igbagbe. A si tọrọ adura gbogbo ilu, ọrọ na le yọ'ri si rere fun wa. Amin.

Ọgbẹni Oyinbo ti orukọ rẹ njẹ J. Harris lo da ọrọ na silẹ, to si bere lọwọ Ọgbẹni J. H. Thomas, Secretary of State—ọrọ na lọ bayi:—Ibere J. H. Harris:—Ẹniti a mba ro ẹjọ ti a si le da lẹbi iku nitori rẹ ni Nigeria ha le gba aṣẹ pataki lọdọ Gomina fun anfani lati haya Lọya, ati pe melo ninu awọn ojidin nirinwo enia o le kan (381) ti Ijọba da l'ẹbi iku, ti nwọn si yẹgi mọ l'ẹsẹ lati iwọn ọdun kẹrin wa lo ri iru aṣẹ pataki yi gba ?

Idahun Secretary of State:—Lọya ko gbọdọ yọju si ẹjọ kẹjọ kan ni Native tabi Provincial Court, Gomina ko si ni agbara lati yọda anfani ati haya Lọya fun ẹnikẹni to l'ẹjọ nibẹ, ṣugbọn Lọya le ṣ'ẹjọ ni Ganran tabi Supreme Court, a si le gbe ẹjọ lati Provincial Court lọ si Supreme Court ti awọn Onidajọ ba ro pe o yẹ bẹ; ṣugbọn ni t'emi, ngo yẹ gbogbo ọrọ na wo, lati ṣe atunṣe ti o ba tọ.

Ibere Macpherson:—Talo tilẹ sọ Lọya pẹlu Provincial Court di ọsan pẹlu oru ti ko gbọdọ f'oju kan ara wọn; talo paṣẹ onikumọ na ?

Idahun Secretary of State:—Mo ti sọ iyatọ to wa larin awọn Kotu mejeji, mo si ti dahun ọpọ-

lọpọ ibere awọn Janma pe ngo yẹ gbogbo ọrọ na wo laipẹ.

Ibere Captain Berkely:—Enyin ha mọ pe ni gbogbo Ilu miran to wa labẹ asia Gẹsi, Ijọba papa nfi owo apo rẹ haya Lọya fun talaka ki talaka ti nwọn ba fẹ ba ro ẹjọ apania ?

Ibere Macpherson:—Ṣugbọn bawo ni awọn "ọga diẹ" ni Nigeria ti ro o ti si, ti Lọya le ṣ'ẹjọ ni Supreme Court, ti ko si gbọdọ kọja ni ita Provincial Court ?

Idahun Secretary of State:—Awọn to ṣe iru ofin bẹ nikan ni nwọn mọ bi nwọn ti ro o si. Nitori bi Ile ṣ ṣẹ Lọya ni Kotu kan, ati aile ṣ'ṣẹ rẹ ni Kotu keji ṣe emi na loju su u, on lo jẹ ki nfẹ wa'di gbogbo ọrọ na wo.

Ibere Macpherson:—Njẹ ẹ ko ha mọ pe ohun pataki pupọ ni fun ẹniti a nba ro ẹjọ apania lati tete ni Lọya lati ibẹrẹ wahala rẹ ?

Idahun Secretary of State:—Nitori iyẹn na gan ti emi papa ro, lo jẹ ki nfẹ wa'di itunbi-inubi ọrọ na finifini.

Ibere J Haris:—Kotu Ilu wo lo ha tun wa lẹhin ti Nigeria ti ko gbọdọ ri Lọya s'oju ?

Idahun Secretary of State:—Kotu Aṣanti, ti agbegbe ilu Gambia, ti Basutoland ati agbegbe iki Gambia, ti Basutoland ati agbegbe Bechuanaland pẹlu nsa fun Lọya barabara bi ẹjọ nla ba de'lẹ.

Ibere J Harris:—A ha le da itọ mi si ileri rẹ lati yẹ ofin ti Nigeria wo, ati iyẹwo na yio kan Ilu mẹta ti a da'rukọ wọn si wọnyi ?

Idahun Secretary of State:—Iwọ wi i, o sọrọ tan, o "dili" rẹ.

Ibere B. Smith:—Ẹ ki yio ha ṣe ohun ti o to nipa ọrọ wọnyi, ki ẹ si jẹ ki Gambari bo "ori buruku" ti awọn aṣiwaju nyin fi silẹ ni abotan ?

Ibere Sir C. Yate:—Ẹ ki yio ha daro wo pẹlu bawo lo ti tọ si ki awọn Ijoye Enia Dudu ma da ẹjọ wọnyi fun ara wọn gẹgẹ bi aṣa ilẹ wọn ?

Idahun Secretary of State:—Ani gbogbo rẹ ni ugo fi s'ero patapata.

Ibere Lieutenant Colonel Meyler:—Ẹ ha mọ pe Kotu to wa ni arọko ilu Borneo ti ko aṣa Nigeria lati ma sa fun Lọya? (bi awọn Musulumi ti nyẹra fun abiru-wereke lori irẹsi) Nitorina ẹ ki yio ha fun ara ilu na ni anfani ati haya Lọya pada bi ?

Idahun Secretary of State:—Nko mo ohun ti Ijọba arọko ilu Borneo nṣe, ṣugbọn ago wadi bi nkan ti ri lọdọ British North Borneo Company.

Ibere Baker:—Ẹ ha mọ pe ọpọlọpọ awọn to ndajọ ni Provincial ati Native Court ni ko gbọ ede ilu arufin ti a nba ro'jọ, nwọn si ni lati gba ohunkohun ti Ogbufọ ba wi. Igbẹhin eyi le ma dara fun ẹniti a nba ro'jọ, nitorina, ẹ ki yio ha tete wo ọran ti Lọya yi ṣe lati le gba ẹjọ wọn ro ?

Idahun Secretary of State:—Awọn ara ilu papa ni Onidajọ Native Court, awọn Oyinbo to nda'jọ ni Provincial Court si ni lati kọ ede ilu kilu ti nwọn ba wa. Nitori oniruuru ede to pọ ni Nigeria, a ko le ṣai ni Ogbufọ nibẹ, bi nwọn ba tilẹ ni anfani ati haya Lọya, iyẹn ko din iṣẹ Ogbufọ ku.

Ibiti ọrọ na de nisisiyi ni eyi o. Aṣ'eke da iṣẹ silẹ fun oriṣa. Ẹniti o da ofin Provincial Court Ordinance yi silẹ ni Nigeria ko to lati yọju tabi lati da si ariyanjiyan ọrọ nipa rẹ ni Igbimọ Ilu Oyinbo—House of Commons.

Ti a ba wipe ofin Provincial Court Ordinance yi ko si l Eko, tani ninu wa ti iṣẹ ko le gbe lọ si idalẹ ibiti nwọn nlo ofin na—ofin na wa ni ibomiran ni Abẹokuta nitosi nbi, o wa ni Ibadan, o wa ni Ijẹbu Ode, ka ma ṣẹṣẹ sọ ti ọna jijin rere. Bi ofin na ba parẹ, awọn Lọya wa yio tubọ ri iṣẹ ṣe, nwọn a si r'aye ati kọ iya pupọ fun awọn ara wa ti iya njẹ ni Kotu idalẹ.

Njẹ bi ko ba si awọn giriki Lọya bi Ọlọla J. Egerton Shyngle, Ologbe Kitoyi Ajasa, Eric Moore, E. J. Alex Taylor, J. T. Nelson Cole, Ọlayimika ati Adeyẹmọ A l a k i j a, Montacute Thompson ati awọn jakanjakan miran l'Eko nko? A ko ṣai mọ pe ọpọlọpọ Lọya lo nhuwa "a don kia" ( I don't care ) si ọrọ ilu.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

## OLUSAKIN'S COLUMN.

### St. Jude's New Church. Ebute Metta.

The new Church Building of St. Jude's Ebute Metta, was dedicated by the Bishop of Lagos, the Rt. Rev. Bishop F. Melville Jones, D.D., on Saturday, the 12th May, 1928, at 3.30 p.m. The Ministers took part in the procession were 57 Anglican Clergy, 5 Wesleyan Methodist Clergy, 2 Archdeacons, and the Chancellor of the Diocese, 2 Wardens, 2 Organists, 31 female Choristers and 53 males Choristers.

The Building is unique and magnificent.. Our congratulation to all concerned and to the Architect J. Bagan Benjamin, Esqr., C.E., The collection was amounted to £25 1s. 10d.

### Birthday.

We congratulate Mr. E. Tommy Scott of Victoria Road and Ebute Metta, for celebrating the 50th Anniversary of his Birth-day on the 1st of May, 1928.

We wish him many happy returns of the day.

### The Collision of Motor Cycle and Push Bicycle at Iddo.

On Saturday last, the 12th inst. at about 3 p.m. Mr. S. E. Falashe Chief Sanitary Inspector, Lagos, sustained

severe injuries. at the result of a collision at Iddo. Mr. Falashe was going home to Ebute Metta on a Motor Bike from Lagos, when he ran over a young man on a push Cycle. Both men were immediately removed to the African Colonial Hospital.

Our sympathy goes to them and we wish them an early recovery.

**The retirement of Mr. G. N. Martins after his present leave.**

Mr. George N. Martins, Supervisor of His Majesty Customs, Port Harcourt, is on 3 months' leave as from the 1st April, 1928.

Mr. Martins arrived Lagos from Port Harcourt by the S.S. *Appam*, on the 11th instant, where he has gone on transfer about 4 years ago, to spend his vacation, before retiring after 39 years' merritorious and faithful service.

**Departure.**

By the S.S. *Appam* which sailed this Port on Friday, the 11th May, 1928, Mr. H. S. Berckley, Police Magistrate, Lagos, was among the passengers, to Plymouth on leave of absence. We understand that H. A. Young, Esqr., K.C., Police Magistrate, Ebute Metta, will relieve him.

**Empire Day Celebration.**

On Thursday next, the 24th May, 1928, there will be a parade of all School children to the Race Course, the Fields, for the usual observation of the Empire day.

God save the King.

**Serious Earthquake in Turkey.**

CASUALTIES IN SMYRNA.

Our Constantinople Correspondent telegraphs :—

There was a serious earthquake in Western Turkey between 2.05 and 2.30 on Saturday morning. The shocks were most severely felt in Smyrna, but disturbances were also felt at places so far apart as Konia and Adrianople. About 20 different shocks were felt in Smyrna, where there has been loss of life and considerable damage to property. According to the latest information 21 persons have been killed and more than 60 injured. Thirty houses and 10 shops have been completely destroyed; six Mosques, many public buildings, and several hundred houses and shops damaged, and the picturesque clock tower siriously damaged. The worst damage appears to have been done at the Village of Torbali, close to Smyrna. *The Times Weekly Edition. 5/4/28.*

**Party of Pilgrims found Dead in Charabanc.**

*Reuter's News Agency.*

JERUSALEM, MONDAY.

A charabanc containing twenty pilgrims crossing the desert at Bagdad going to Beirut lost its way. The vehicle was located later by a British Aeroplane but all the pilgrims were dead before help could reach them.—*Daily Times, 8/5/28.*

OLUṢAKIN.

---

## IROHIN LATI IBADAN.

E. O. Shobayọ, Ijẹbu gigun, ẹni pupa ti o ngba owo kiri lorukọ Alufa J. S. Adejumọ ti Ile Ifẹ. O ti bẹrẹ nkan wọnyi ni oṣu *March* titi di *April 17* ti o ti inu ẹwọn de inu ẹwọn. Awọn mẹta ni wọn; ọkan njẹ Olowu, o gba ọna Akurẹ titi de Onbe o nsọ ni gbogbo *C.S.M. Station* ti o ba de ti nwọn ti mọ Alufa yi pe, Alufa Adejumọ lo ran on niṣẹ, oni *motor* fi on silẹ lọna owo tan lọwọ on, o gba owo lọwọ wọn ati onjẹ, o ṣe bẹ ni Igbara Oke, Ero, Ilara, Akurẹ, ati ni Ọwọ ni wọn ti mu. O mu iwe lọ sọdọ Alufa C. W Jebb, Oyinbo, lati tan jẹ, Alufa Jebb ko mọ pe ole ni Shobayọ nṣe o ran lọwọ; lẹhinna ni o tọ Ọgbẹn, Gabber ti *(Salvation Army)* Ogun Igbala lọ ati Alufa *C.M.S.* T. F. Aderin ti Ọwọ, lalẹ rẹ ni wọn mu wipe o ji iwe pẹlu nkan miran, ki a ma ba lọ, wọn fi si ẹwọn oṣu mẹta l Ọwọ. O tun wa si Ibadan lati pade Alufa Adejumọ ni *Court* Agodi, Ibadan, awọn mejeji ko ri ara ri. Ẹ wo bajẹ o. E. O. Shobayọ gbe *letter* tirẹ wa si Ibadan, o gba £6. 10s. lọwọ Alufa J. A. Okuṣehinde ni Arẹmọ, Ibadan, £2. 10s. lọwọ Alufa E. M. Alalade Kudẹti, Ibadan, ati £5 lowọ Alufa Agba R. S. Oyebọde, ni Ibadan, ati £5 lọwọ *Archdeacon* Eko.

A tun gbọ o tọ *Bishop* Jones wa l'Eko o bere owo *Bishop* Jones bọ lọwọ rẹ nipa pe ki o lọ gba *(Invoice)* itu mọ rẹ ni ẹri ọja to ra, ohun ti Alufa Adejumọ na ran wa lọwọ awọn ti o ti ra ọja, bi Pan, Ẹfun, ati Ọda, a lọ ni *Bishop* ri ko si ri abo Shobayọ mọ, titi o fi sa lọ si *Bookshop* ki ọwọ to tẹ, a mu E. O. Shobayọ wa si *Court* Agodi ni Ibadan ni ọjọ 17 oṣu *April*, ti o si jẹwọ niwaju Adajọ, ko si jẹ ki Alufa Adejumọ ki o sọrọ rara nitori Adajọ ni Alufa Adejumọ ko ran niṣẹ.

Ẹnyin ara Eko, Ibadan, Ifẹ, Ọwọ tabi ilu ibomiran, ẹ jọwọ ẹ wadi ki ẹ to fi owo fun awọn oniro ba wọn yi.

Shobayọ wọ ẹwọn ọdun kan.

Ara Ijẹbu Ode ni awọn mejeji nṣe.

Kini ṣe ti ẹnyin Ijẹbu kakiri ilu to jẹ pe iru ni nyin ẹ ki wọn ninu ọbẹ, eyi ara.

---

## ISIN PATAKI TI AWỌN AFRICAN BETHEL CHURCH ṢE NI ỌSẸ TO KỌJA 6TH MAY, 1928.

Isin pataki ti a ṣe ni ọjọ na jẹ isin to wu enia lori debipe enia le ronu wo ko si tun ri bi atupa ina Ọlọrun Bethel ẹniti nbọ awọn enia tirẹ ti ntan ni ọjọ yi nigbati Oriṣiriṣi ẹgbẹ lokunrin lobinrin bi nwọn ti ndide ti wọn si nkọ Orin to larinrin a ko tilẹ mọ pe ilẹ nṣu nigbati a ngbadun awọn ẹgbẹ wọn yi, ti Alufa wa Rev. Abọyade Cole joko lori aga ti o si npe olukuluku ẹgbẹ ni ikankan kosibotiri ni alẹ ọjọ yi orukọ awọn Ẹgbẹ na ni wọnyi. (1) The chori (2) Ladies Guild, (3) Spiritual Progress Society (4) Ẹgbẹ Ireti, (5) Young-women Xtian Union (6) Ẹgbẹ Ifẹ, (7) Young-ladies friendly Society, (8) Young-men Christian Guild, (9) The Little Flock Society (10) Young Men Auxiliary Association (11) The African Lady's Brigade 1st Coy, (12)

The Boy Scouts (5th & 11th troops) (13) The Cartedral Boys Mornning Star Society, (14) Parish committee represented by Mr. J. H. E. Willoughby. Bayi ni aṣe awọn eto na lọ, Agẹmọ bimọ rẹ na wayi o aimọjo dọwọ rẹ o, lotọloto ni mo wi fun nyin gẹgẹ bi Jesu Oluwa ti ma nsọ fun awọn omọ ẹhin rẹ bayi nigba miran lati ba dan ifẹ ọkan wọn wo bo ti gbona si, bẹna lafẹ bi ẹnyin ara wa loni pe tani ifẹ Ọlọrun wa lọkan rẹ gẹgẹ bi Enia Dudu nitori pe ifẹ ni akoja ofin. Ẹ jẹ ki a me gbadura lai sinmi ki Ọlọrun Olodumare ko fi oju anu wo Ijọ African Church ki o si ṣe iranlọwọ fun wa ninu ohun pataki ti a gbe kalẹ, iṣẹ wa ni ki a mu ara wa giri ki a si le pari iṣẹ Ile Ọlọrun titun ti a nkọ na pẹlu ifẹ ati alafia.

Rev. Abọyade Cole mo gbadun rẹ, ki Ọlọrun fi iṣẹ rẹ yin ọ, amin. Ki o si jẹ ki Ijọ enia dudu di mimọ fun gbogbo Orilẹ Ede ki a si le ma sin Ọlọrun wa bo ti tọ ati bo ti yẹ. A dupẹ loni pe enia dudu gbogbo patapata Yoruba, Hausa, Kotonkori, awọn Agonyin papa lati ibi ti ilẹ awa enia dudu ti bẹre a ni gbagbọ pe wọn mọ orukọ Ọlọrun pe loni, ṣugbọn kini ku fun wa loni o ku Ifẹ, igbagbọ, ireti. Ṣugbọn ninu awọn mẹtẹta yi Bibeli sọ fun wa pe eyiti o tobi ju ni ifẹ eyi ni nipe bi aba ni ifẹ si ara wa gbogbo ọrọ wa yio ma lọ dede, ẹ jẹ ki bẹni wa, ki o jẹ bẹni ki alafia Ọlọrun to ju imọran gbogbo lọ ko wa pẹlu wa ki a le pari ile Ọlọrun titun ti a nkọ na ni alafia ni agbara ifẹ Olodumare Baba wa ọrun, Amin bẹni kori.

Emi ni tinyin,

RIRO NITI ENIA ỌLỌRUN LOLUṢE.

---

ORI III.

## IWA—ẸGBẸ KIKO ATI APẸRẸ.

*(Translated from "Character by Dr. Smiles").*

APA KẸSAN.

Ọpọlọpọ awọn ọdọmọkunrin ti o jẹ oninu rere ni o ni awọn akọni wọn, awọn ti nwọn di ni oriṣa ti nwon a ma gba fun papa ti awọn ọdọmọkunrin yi ba jẹ ọkawe enia. Bayi ni a ri ipe nigbat Allan Cunningham nkọ iṣẹ ile mimọ ni Nithsdale, o fi ẹsẹ rinlẹ lọ titi de Edingburgh ki o ba le mọ Sir Wltter Scott bi o ti nrin lọ ni ita. A gba fun ọmọde yi, irufẹ ọkan ti o ni eyiti o mu fi ẹsẹ le ọna bayi, si jọ ni loju.

A gbọ nipa Sir Joshua Reynolds pe nigbati o wa ni ọmọ ọdun mẹwa o nọga larin ogunlọgọ enia o fi ọwọ tọ Pope bi ẹnipe aṣẹ kan wa ninu fifi ọwọ kan Pope.

O pẹ titi lẹhin eyi Haydon ẹniti iṣe iṣe ọna aworan yọ lati ri Reynold ati lati fi ọwọ tọ nigbati o lọ bẹ ilu rẹ wo.

Rogers ọkowe orin ma nsọ bi o ti wa ni ẹmi on to, nigbati on wa ni ọmọde lati mọ Dr. Johnson; ṣugbọn nigbati o de ẹnu ọna ile rẹ ni Bolt Court ti o fẹ kan ilẹkun aiya rẹ ja, o yi pada biri.

Bẹna ni Ologbe Isaac Disraeli lọ si Bolt Court nigbati o wa ni ọmọde fun ọkan na; on tilẹ ṣe akin o kan ilẹkan, ṣugbọn ẹnu ya nigbati ọmọ-ọdọ kan jade si i ti o sọ fun pe ọkunrin na oṣe-iwe-itumọ ṣẹṣẹ dakẹ ni.

Ni ida keji, awọn gan-ni-gan-ni enia, awọn ti ko fẹran enia, ko le fi tọ-kan-tọ-kan gba fun awọn ẹlomiran. Nwọn ṣe oriburuku niti pe nwọn ko mọ riri, ki a ma sọ ti pe nwọn ko mọ ọw fun awọn ẹni rere, tabi fun nkan rere. Awọn enia jati-jati a gba fun nkan jai-jati. Loju pọn-ni-pọn-ni enia ko si enia kan ti o jẹ enia ju awọn ti o npọn lọ. Kekere ṣẹgan-ṣẹgan ko mọ pe ẹnikan tun wa ti o ju agba ṣẹgan-ṣẹgan lọ. Bi egun enia ti ta to ni ẹniti nta ẹru ti di ye le enia.

Ni ọjọ kan nigbati Sir Godfrey Kneller nsọ fun onișowo Guinea kan loju Pope pe, awọn enia meji ti o to bi ju laiye ni o wa niwaju on yi, o dahun o ni: "Emi ko mọ bi o ti to, ṣugbọn iwọ ko wun mi. Emi a ma ra igiripa-kunrin kan ti kato, ti o ju ki a pa ẹnyin mejeji pọ ṣe ọkan lọ, ni ọkẹ mejilelogoji!"

Lotitọ ni Rochefoucauld ninu awọn aṣayan ọrọ rọ sọ pe, ofo kan ti o ba ṣe ẹnti o tilẹ jẹ kori-ko-sun ẹni, ki ṣai ni ibikan ti o gba dun mọ ni, ko i dun ni de ọkan, ṣugbọn awọn enia ti ko ni lari, awọn enia lasan ni nma vọ nigbati nkan ko badara fun ọmọ-ẹni-keji, wọn, ti inu a ma bi wọn nigbati nkan ba dara fun awọn ẹlomiran.

Awọn kan wa ti inu wọn buru si enia, o ṣe lara wọn!

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌBA

The scientific Discovery of the nineteenth century for Female sufferers is

# WIRELESS FEMALE PILLS

***A sure remedy against all kinds of monthly disorders experienced by women, and an effective vitaliser against barreness. 4/6d per bottle of 72 Pills.***

# COOLING BLOOD PURIFIER

***A powerful blood purifier, cleansing the system of all impurities—approved by competent Medical Authorities. 7/6d***

# LIFE TONIC TABLET.

***A Renewer of Youth. 3/-***

# KADUNA BALM

***'The family Balm' applicable in 100 ways! 1/-.***

At present sold only at :—

# Iyin Oluwa Medicine Stores

*Head Office* :—88, Broad Street, Lagos,

6, Martins Street,

41, Alli Street, Faji Market,

22, Agarawu Street,

109, Griffith Street, Ebute-Metta

**Note our new Shop's address.**

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

REMO FUN OKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati orişirişi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe ṣişẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy for Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist,*

The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos

"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to:—

MR. MOSES O. COKER,
Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
(Manchester) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specific acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address*:—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIRẸMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

# TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

***Always at everybody's service at Tinubu Square.***

For Terms, Apply to:—

**A. B. Williams,**
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

### Ni No. 63, Ehingbeti, Eko,

———— : o : ————

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orișirisi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ loriṣiriṣi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.